# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KẸ́JỌ, ỌDÚN 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KẸJỌ, ỌDÚN 2024**
**ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀**
**GBÀ JÈHÓFÀ DÁ AYÉ**

1. Gbà Jèhófà dá ayé,
Gbàt'ó sọ̀rọ̀ t'ó sì ṣẹ,
Àwọn Ángẹ́lì nkọrin
Alelúyà gb'ọ̀run kan.

2. Orin 'yìn l'a kọ lórọ̀,
Gbàt'a bí Olùgbàlà,
Orin 'yìn ni a sì kọ,
Nígbàt'ó dìgbèkùn lọ

3. Gbàt'ayé y'ó kọjá lọ
Ìyìn ó gb'ọjọ́ nà kan;
"Gbàt'a ó d'áyé titun,
Orin ìyìn l'a ó kọ.

4. Àwa ó ha dákẹ́ bí,
Títí 'jọba nà ó dè?
Bẹ́kọ̀! Ìjọ ó ma kọ,
Orin mímọ́ àt'ìyìn.

5. Ènìyàn mímọ́ l'áyé,
Nf'ayọ̀ kọrin ìyìn nà;
Nípa 'gbàgbọ́ ni wọ́n nkọ,
Bí wọ́n ó ti kọ l'ókè.

6. Nígbà ẹ̀mí ó bà pin,
Orin ni ó ṣẹ́gun ‘kú,
Nínú ayọ̀ àìlópin,
Wọn ó ma kọrin títí.

## WO OLÚWA L’ÁWỌSÁNMÀ

1. Wo Olúwa l’áwọsánmà,
Ó mbọ̀ l’ógo l’ọ́lá Rẹ̀,
Ẹnit’a pa fún ẹlẹ́ṣẹ̀,
Mbọ̀ pẹ̀lú ángẹ́lì Rẹ̀;
Alelúyà! Alelúyà!
Ó wá s’áyé wá jọba.

2. Gbogbo ẹ̀dá, wá wo Jésù,
Aṣọ ògo l’a wọ̀ fun,
Àwọn t’ó gàn, àwọn t’ó pa,
T’ó kàn mọ́ àgbélèbú,
Wọ́n ó sọkún, Wọ́n ó sọkún,
Bí wọ́n bá rí Mèssíàh.

3. Gbogbo ilẹ̀, òkun àt’òkè,
Ọ̀run àt’ayé yóò fò lọ,
Àwọn tó kórira Rẹ̀ yóò dàmú,
Gbọ́ ipè, kéde ọjọ́ nà,
Wásí ‘dajọ́, wásí ‘dajọ́,
Wásí ‘dajọ́, wa lónì.

4. Ìràpadà t’a ti nretí,
Ó dé pẹ̀lú ògo nlá,
Àwọn tí a gàn pẹ̀lú Rẹ̀,
Y’ó pàdé Rẹ̀ lój’ọ̀run,
Allelúyà, Allelúyà,
Ọjọ́ Olùgbàlà dé.

5. Àwọn apá ìyà t’Ó jẹ,
Hàn lí ara dídán Rẹ̀,
Àwọn ẹni ìràpadà,
Wólẹ̀, fún t’ayọ̀ t’ayọ̀,
Pẹ̀l’áyọ̀ nlá,
L’à nwo àwọn apá nà.

6. Bẹ́ni Àmín! K’ájúbà Rẹ̀,
Lór’ìtẹ́ Rẹ̀ àìlópin,
Olùgbàlà gba agbára,
Ògo àt’ijọba Rẹ̀,
Jáh-Jèhófà, Jáh-Jèhófà,
Ọlọ́run àìkú, má bọ.

## <u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>

1. Láti oṣù Kẹjọ, ọdún 2024 yìí lọ, gbogbo ìdibàjẹ́ òkùnkùn kò tún ní lépa ayànmọ́ mi mọ́, yóò dópin lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Ọfà ìyówù tí wọ́n ta sí mi láti jẹ́ kí nní àdánù nípa ètò ìṣúná owó yóò fi ayé mi sílẹ̀ lónìí, yóò padà sọ́dọ̀ ẹni tí ó rán an nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.

3. Ọlọ́run, dìde nínú àrá agbára Rẹ, jẹ òṣì ilé bàbá mi run lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí àwọn ọ̀tá mi di oúnjẹ fún ara wọn, ní orúkọ Jésù.
5. Iná ìtúsílẹ̀, dìde lónìí, pa gbogbo ààlè tí wọ́n gbé sórí ìṣerere mi run, ní orúkọ Jésù.
6. Ọlọ́run, dìde lónìí, fi àwọn ọ̀tá ayànmọ́ mi sínú àjálù tí wọn kòlè bọ́ kúrò nínú rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Bàbá mi, nípa àánú Rẹ, jẹ́ kí gbogbo ohun-ìjà ogun àwọn ọ̀tá mi bẹ̀rẹ̀ siní kọ ojú ìjà sí wọn, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**3 Jòhánnù 2:** Olùfẹ́, èmi n gbàdúrà pé nínú ohun gbogbo, kí ó lè ma dára fún ọ, kí o sì ma wà ní ìlera, àní bí ó ti dára fún ọkàn rẹ.

**Fílíppì 1:6:** Ohun kan yì ṣá dá mi lójú, pé ẹnití ó ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere nínú nyín, yóò ṣe àṣepé rẹ̀ títí fi di ọjọ́ Jésù Krístì.

**Jòhánnù 10:10:** Olè kì íwá bíkòṣe láti jalè, àti láti pa, àti láti parun; èmi wá kí nwọ́n lè ní ìyè, àní kí wọ́n lè ní i lọ́pọ̀lọpọ̀.
**Kòlóssè 1:13:** Ẹnití Ó ti gbà wá kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, tí ò sí ṣí wa nípò sínú ìjọba àyànfẹ́ ọmọ Rẹ̀:

**1 Kọ́ríntì 4:20:** Ńítorí ìjọba Ọlọ́run kì íṣe nínú ọ̀rọ̀, bíkòṣe nínú agbára.

**1 Kọ́ríntì 6:14:** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run ti jí Olúwa dìde, yóò sì jí àwa dìde pẹ̀lú nípa agbára Rẹ̀.

**Éfésù 3:20:** Nj̣ẹ́ ẹnití ó lè ṣe lọ́pọ̀lọpọ̀ ju gbogbo èyítí à mbèrè tàbí tí a nrò lọ, gẹ́gẹ́ bí agbára tí nṣiṣẹ́ nínú wa.

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, rán ìdàrúdàpọ̀ lòdì sí gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fi ìṣerere mi ṣòfò, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ìwé ìrántí tí àwọn ọ̀tá mi ti padé lòdì sími, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, ṣí nípa iná báyìí, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn àlàjá ọlọ́jọ́ pípẹ́ mi, níbo ni ẹ wà? Kí ètò yìí tó parí, wámirí nípa iná, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, jẹ́ kí àrá Ọlọ́run ṣàwárí, kí ó sì parun agbára tí ó wí pé nkò ní gbádùn ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Agbárakágbára tí ó gba iṣẹ́ búburú ṣe lòdì sí àti tẹ̀síwájú mi, ilẹ̀ ìsìnkú rẹ rè é, ṣubú lulẹ̀, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.